# Ìfaramọ́
## Consent

**ÀKÍYÈSÍ SÍ ÀWỌN ONÍBÀÁRÀ:** Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ìgbàlódé àti Ìlera (DSHS) le ràn ọ́ lọ́wọ́ dáradára tí a bá le ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn aṣojú míràn àti akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tó mọ̀ ọ́ àti ẹbí rẹ. Nípa fífi ọwọ́ sí fọ́ọ̀mù yìí, o fún DSHS láàyè àti àwọn aṣojú àti ẹni kọ̀ọ̀kan tí a kọsílẹ̀ nísàlẹ̀ láti lò àti láti pín àlàyé àṣírí nípa rẹ. DSHS kò le sẹ́ àwọn ànfàní rẹ tí o ko bá bu ọwọ́ lu fọ́ọ̀mù yìí àyàfi tí a bá nílò ìyọ̀nda rẹ láti pinnu àmúyẹ rẹ. Tí o kò bá bu ọwọ́ lu fọ́ọ̀mù yìí, DSHS sì tún le pín àlàyé nípa rẹ títí dé ibi tí òfin gbà láyè. Tí o bá ní àwọn ìbéèrè nípa bí DSHS ti ń pín àlàyé àṣírí oníbàárà tàbí àwọn ẹ̀tọ́ ìpamọ́ rẹ, jọ̀wọ́ kàn sí Àkíyèsí DSHS ti Àwọn Ìṣe Ìpamọ́ tàbí bèrè lọ́wọ́ ẹnití ó fún ọ ní fọ́ọ̀mù yìí.

| ÌDÁNIMỌ̀ ONÍBÀÁRÀ: | | |
|---|---|---|
| ORÚKỌ | DÉÈTÌ ÌBÍ | NỌ́MBÀ ÌDÁNIMỌ̀ |
| ÀDÍRẸ́SÌ | ÌLÚ | ÌPÍNLẸ̀ / KÓÒDÙ ÌFÌWÉRÁNṢẸ́ |
| NỌ́MBÀ Ẹ̀RỌ ÌBÁNISỌ̀RỌ̀ (PẸ̀LÚ KÓÒDÙ AGBÈGBÈ) | ÀLÀYÉ MÍRÀN | |

**ÌFARAMỌ́:**

Mo faramọ́ ilò àlàyé àṣírí nípa mi láàrín DSHS láti ṣètò, pèsè, àti láti darí àwọn iṣẹ́, ìtọ́jú, ìsanwó, àti àwọn ànfàní fún mi tàbí fún àwọn èrèdí míràn tí òfin fún láṣẹ. Mo tún fún DSHS ní àyè síwájú síi àti àwọn aṣojú, olùpèsè, tàbí àwọn ènìyàn tí a kọ sísàlẹ̀ láti lo àlàyé àṣírí mi kí wọ́n sì sọ fún ara wọn fún àwọn èrèdí wọ̀nyí. A le fi ẹnu pín àlàyé tàbí nípa ìfiṣọwọ́ dátà orí kọ̀npútà, lẹ́tà, tàbí fífi ọwọ́ jíṣẹ́.

Jọ̀wọ́ ṣàyẹ̀wò gbogbo ohun ìsàlẹ̀ tí a fikún ìfaramọ́ yìí ní àfikún sí DSHS kí o sì dá wọn mọ̀ nípa orúkọ àti àdírẹ́ẹ̀sì:

- ☐ Àwọn olùpèsè ìtọ́jú ìlera: ______
- ☐ Àwọn olùpèsè ìtọ́jú ìlera ọpọlọ: ______
- ☐ Àwọn olùpèsè iṣẹ́ àṣìlò ògùn olóró: ______
- ☐ Àwọn olùpèsè agbaṣẹ́ṣe DSHS míràn: ______
- ☐ Àwọn ètò ilé gbígbé: ______
- ☐ Àwọn ilé-ìwé agbègbè tàbí ilé-ìwé gíga: ______
- ☐ Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ọgbà Ẹ̀wọ̀n: ______
- ☐ Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ààbò Iṣẹ́-ṣíṣe àti àwọn alájọṣiṣẹ́ iṣẹ́-ṣíṣe: ______
- ☐ Alákòóso Ààbò Ìgbàlódé tàbí aṣojú ìjọba àpapọ̀ míràn: ______
- ☐ Wo àkójọ tí a sopọ̀
- ☐ Òmíràn:

Mo faramọ́ mo sì fúnláṣẹ láti pín àwọn àkọsílẹ̀ àti àlàyé wọ̀nyí (ṣàmì sí gbogbo èyí tó kàn):

- ☐ Gbogbo àkọsílẹ̀ oníbàárà mi
- ☐ Àwọn àkọsílẹ̀ lórí àkójọ tí a sopọ̀
- ☐ Àwọn àkọsílẹ̀ wọ̀nyí nìkan
  - ☐ Ìtàn ẹbí, ìgbàlódé àti iṣẹ́
  - ☐ Àlàyé ìtọ́jú ìlera
  - ☐ Àwọn ètò ìtọ́jú tàbí abójútó
  - ☐ Àwọn àkọsílẹ̀ ìsanwó
  - ☐ Àwọn àyẹ̀wò ẹnikọ̀ọ̀kan
  - ☐ Ilé-ìwé, ẹ̀kọ́, àti ìkọ́ni
  - ☐ Òmíràn (àkójọ):

**JỌ̀WỌ́ KÍYÈSÍ: Tí àkọsílẹ̀ oníbàárà rẹ bá ní èyíkéyìí àlàyé wọ̀nyí, o tún gbọ́dọ̀ parí abala yìí láti ṣafikún àwọn àkọsílẹ̀ wọ̀nyí.**

Mo yọ̀nda láti ṣàfihàn àwọn àkọsílẹ̀ wọ̀nyí (ṣàmì sí gbogbo èyí tó kàn):

☐ Ìlera ọpọlọ ☐ Àwọn èsì àyẹ̀wò HIV/AIDS àti STD, àtúpalẹ̀, tàbí ìtọ́jú ☐ Àṣìlò Ògùn Olóró

- **Ìfaramọ́ yìí wúlò fún ☐ ọdún kan ☐ títí DSHS bá fi nílò àwọn àkọsílẹ̀, tàbí ☐ títí ______ (déètì tàbí ìṣẹ̀lẹ̀).**
- **Mo le yọ tàbí gba ìfaramọ́ yìí padà nígbà kugbà ní àfọwọ́kọ, ṣùgbọ́n èyí kò ní kan èyíkéyìí àlàyé tí a ti pín tẹ́lẹ̀.**
- **Ó yé mi wípé èyíkeyìí àkọsílẹ̀ tí a pín lábẹ́ ìfaramọ́ yìí le má ní ààbò mọ́ lábẹ́ òfin tó kan DSHS.**
- **Ẹ̀dà kan ti fọ́ọ̀mù yìí wúlò láti yọ̀nda àṣẹ mi láti pín àwọn àkọsílẹ̀.**

| ÌBUWỌ́LÙ | DÉÈTÌ | ẸLẸ́RÌÍ / ÀṢẸ (BUWỌ́LÙ KỌ ORÚKỌ, TÓ BA YẸ) | DÉÈTÌ |
|---|---|---|---|
| ÌBUWỌ́LÙ ÒBÍ TÀBÍ AṢOJÚ (TÓ BÁ YẸ) | | NỌ́MBÀ Ẹ̀RỌ ÌBÁNISỌ̀RỌ̀ (PẸ̀LÚ KÓÒDÙ AGBÈGBÈ) | DÉÈTÌ |

Tí ń kò bá sí nínú àkọsílẹ̀ náà, mo ní àṣẹ láti buwọ́lù nítorí èmi ni: (fi ẹ̀rí àṣẹ síí)

☐ Òbí ☐ Alágbàtọ́ Lọ́na Òfin (so àṣẹ ilé-ẹjọ́ pọ̀) ☐ Aṣojú àdáni ☐ Òmíràn:

ÀKÍYÈSÍ SÍ ÀWỌN OLUGBÀ ÀLÀYÉ: **Tí àwọn àkọsílẹ̀ wọ̀nyí bá ní àlàyé nípa HIV, STD, tàbí AIDS, o le má ṣàfihàn àlàyé náà mọ́ láì gba àṣẹ ní pàtó lọ́wọ́ oníbàárà.** Tí o bá ti gba àlàyé tó jọmọ́ **àṣìlò ògùn tàbí otí líle** nípasẹ̀ oníbàárà, o gbọ́dọ̀ ṣafikún gbólóhùn wọ̀nyí nígbàtí o bá ń ṣàfihàn àlàyé bí 42 CFR 2.32 ti bèrè:

A ṣàfihàn àlàyé yìí fún ọ láti àwọn àkọsílẹ̀ èyítí òfin àṣírí Ìjọba Àpapọ̀ ń tọ́jú (42 CFR part 2). Àwọn òfin Ìjọba Àpapọ̀ fi òfin dè ọ́ láti máṣe ṣàfihàn àlàyé yìí àyàfi tí a bá gbà ọ́ láàyè nípa ìyọ̀nda àkọsílẹ̀ láti ọ̀dọ̀ ẹni tókàn tàbí bí 42 CFR part 2 ti gbà láyè. Àṣẹ gbogbogbò fún ìgbéjáde ti àlàyé ìtọ́jú ìlera tàbí òmíràn ni KÒ tó fún èrèdí yìí. Àwọn òfin Ìjọba Àpapọ̀ dènà èyíkéyìí ìlò àlàyé láti tọpinpin ìwà ọ̀daràn tàbí jẹ́jọ́ èyikéyìí aláìsàn àṣìlò ògùn olóró tàbí ọtí líle.

## ÀWỌN ÌTỌNI FÚN PÍPARÍ FỌ́Ọ̀MÙ ÌFARAMỌ́

**Èrèdí:** Lo fọ́ọ̀mù yìí nígbàtí o nílò ìfaramọ́ láti lo àlàyé àṣírí nígbàdégbà nípa oníbàárà kan láàrín DSHS tàbí láti ṣàfihàn àlàyé náà sí àwọn aṣojú míràn láti darí àwọn iṣẹ́ tàbí fún ìtọ́jú, ìsanwó tàbi àwọn iṣẹ́ aṣojú tàbí fún àwọn èrèdí míràn lábẹ́ òfin. Àwọn oníbàárà ni àwọn ènìyàn tí ń gba ànfàní tàbí iṣẹ́ lọ́wọ́ DSHS.

**Ìlò:** Kún fọ́ọ̀mù yìí lórí ẹ̀rọ tó bá ṣeéṣe láti le rọrùn láti kà, **O gbọ́dọ̀ kún fọ́ọ̀mù ọ̀tọ̀ fún ẹnìkọ̀ọ̀kan, àti àwọn ọmọdé.** "Ìwọ" nínú àwọn ìtọ́ni túmọ̀ sí òṣìṣẹ́ DSHS àti "ìwọ" lórí fọ́ọ̀mù náà túmọ̀ sí oníbàárà. Pínpín àwọn àkọsílẹ̀ pẹ̀lú ìlò àti àfihàn àlàyé àṣírí nípa oníbàárà kant.

**Àwọn Abala Fọ́ọ̀mù:**

ÌDÁNIMỌ̀:

- Orúko: Pèsè orúkọ ti oníbàárà kan ṣoṣo lórí fọ́ọ̀mù kọ̀ọ̀kan. Ṣàfikún èyíkéyìí àwọn orúkọ àtijọ́ tí oníbàárà ti le lò nígbàtí ó ń gba àwọn iṣẹ́.
- Déètì Ìbí: Nílò láti dá oníbàárà mọ̀ láàrín àwọn ènìyàn tó ní orúkọ kannáà.
- Nọ́mbà Ìdánimọ̀: Pèsè nọ́mbà ìdánimọ̀ oníbàárà tàbí àfidámọ̀ míràn bíi nọ́mbà ààbò ìgbàlódé (kò nílò) láti ṣèrànwọ́ dídá àwọn àkọsílẹ̀ mọ̀ àti ìtàn ìtọpinpin ati àwọn iṣẹ́ tí a gbà.
- Àdírẹ́ẹ̀sì àti ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀: Àfikún àlàyé tí yóò ṣèrànwọ́ láti wá àti láti dámọ̀ tàbí kíkàn sí oníbàárà náà.
- Òmíràn: Fi sínú àpótí náà èyíkéyìí àlàyé tó le ṣèrànwọ́ láti wá àwọn àkọsílẹ̀ tó le pẹ̀lú àwọn abala DSHS tó lọ́wọ́ sí àwọn iṣẹ́, orúkọ àwọn mọ̀lẹ́bí, tàbí àlàyé pàtakì míràn.

ÌFARAMỌ́ (ÌFÚNLÁṢẸ):

- Àwọn aṣojú tàbí ènìyàn tí ń pàrọ̀ àkọsílẹ̀: Tí oníbàárà bá parí fọ́ọ̀mù yìí ń gbà ìlò àti pínpín àlàyé àṣírí láàyè láàrín gbogbo DSHS. DSHS yóò le ṣàfihàn sí yóò sì gba àlàyé àṣírí láti ọ̀dọ̀ àwọn aṣojú òde tàbí àwọn ènìyàn tí a kọsílẹ̀. Pèsè àlàyé ìdánimọ̀ nípa àwọn aṣojú tàbí olùpèsè, pẹ̀lú orúkọ, àdírẹ́ẹ̀sì tàbí ibi tó wà tó bá ṣeéṣe. O tún le so àkójọ àwọn aṣojú pọ̀ tí a gbà láàyè láti pín àlàyé èyítí oníbàárà gbọ́dọ̀ buwọ́lù.
- Àfikún àlàyé: Àwọn oníbàárà gbọ́dọ̀ sọ irú àwọn àkọsílẹ̀ tó wà nínú àkóónú náà. Àwọn oníbàárà le jẹ́ kí gbogbo àkọsílẹ̀ wà nílẹ̀ tàbí le dín àwọn àkọsílẹ̀ kù nípasẹ̀ déètì, ẹ̀yà tàbí orísun àkọsílẹ̀. Tí oníbàárà kan kò bá buwọ́lu ìfaramọ́ tàbí kò sọ nípàtó àkọsílẹ̀ kan, pínpín àkọsílẹ̀ náà ni a ó sì gbà láàyè lábẹ́ òfin. O le so àkójọ àwọn àkọsílẹ̀ tó ní kan pọ̀ èyítí oníbàára gbọ́dọ̀ buwọ́lù. Tí èyíkéyìí àkọsílẹ̀ bá ní àlàyé tó jọmọ́ ìlera ọpọlọ (RCW 71.05.620), HIV/AIDS tàbí àyẹ́wò tàbí ìtọ́jú STD (RCW 70.02.220), tàbí àwọn iṣẹ́ ògùn olóró àti ọtí líle (42 CFR 2.31(a)(5)), oníbàárà gbọ́dọ̀ ṣàmìsí àwọn abala wọ̀nyí ní pàtó láti yọ̀nda pínpín àwọn àkọsílẹ̀ wọ̀nyí. Fọ́ọ̀mù yìí yẹ láti ṣàfikún àwọn àkíyèsí ìlera ọpọlọ lábẹ́ 45 CFR 164.508(b)(3)(ii) àti fọ́ọ̀mù ọ̀tọ̀ ni a gbọ́dọ̀ kún láti ní àwọn àkọsílẹ̀ náà.
- Ìgbà: Ṣàfikún déètì ìmúdópin fún àkóónú náà tí ń fún ètò rẹ ní èrèdí tàbí bí òfin ti pèsè.
- Níní Òye: Ṣàrídájú wípé oníbàárà ní òye irú àṣẹ tí a yọ̀nda àti ọ̀nà àti ìdí tí a ó fi pín àlàyé náà. Tó bá nílò, lo fọ́ọ̀mù tí a túmọ̀ àti ògbùfọ̀ tàbí ka fọ́ọ̀mù náà sókè. Tí oníbàárà bá nílò ọ̀pọ̀ àlàyé, pèsè àfikún ẹ̀dà ti Àkíyèsí Àwọn Ìṣe Ìpamọ́ ti DSHS tàbí kàn sí oníbàárà sí ọ̀gá àfihàn gbogbogbò fún ìpín rẹ.

ÌBUWỌ́LÙ:

- Oníbàárà: Ní onibàárà tàbí ọmọ kan tó ju ọjọ́-orí ìfaramọ́ lọ (13 fún àwọn iṣẹ́ ìlera ọpọlọ àti ògùn olóró àti ọtí líle; 14 fún HIV/AIDS àti àwọn STD míràn; èyíkéyìí ọjọ́-orí fún fètò sọ́mọ bíbí àti oyún ṣíṣẹ́; 18 fún ìtọ́jú ìlera àti àwọn àkọsílẹ̀ míràn) buwọ́lù àpótí yìí kí o sì fi déètì ìbuwọ́lù síi. Oníbàárà le rọ́pò àmì kan nínú àpótí yìí tí o jẹ́rìísí.
- Ẹlẹ́rìí tàbí Aláṣẹ: A le nílò ẹlẹ́rìí tàbí aláṣẹ kan láti jẹ́rìísí ìdánimọ̀ rẹ tí o kò bá fa fọ́ọ̀mù yìí sílẹ̀ lójúkojú tàbí tí ètò kan bá nílò ìjẹ́rìísí. Ẹni yìí gbọ́dọ̀ buwọ́lù kó sì kọ orúkọ rẹ̀.
- Òbí tàbí Asojú Míràn: Tí oníbàárà náà bá jẹ́ ọmọdé tí ko tó ọjọ́-orí ìfaramọ́, òbí tàbí alágbàtọ́ kan gbọ́dọ̀ buwọ́lù. Tí ọmọ náà kò bá yẹ fún ọjọ́-orí ìfaramọ́ fún gbogbo àkọsílẹ̀ tí a fẹ́ pín, àti ọmọ àti òbí gbọ́dọ̀ buwọ́lù. Tí a bá ti wípé oníbàárà náà kò kójú òṣùwọ̀n lábẹ́ òfin, alágbàtọ́ tí ilé-ẹjọ́ ti yàn gbọ́dọ̀ buwọ́lù kó sì pèsè ẹ̀dà kan ti àṣẹ yíyàn. Tí ẹlòmíràn bá ń buwọ́lù lórúkọ míràn (èyí pẹ̀lú ẹni kan tó ní agbára aṣojú tàbí aṣojú ilé), ṣàmìsí "òmíràn" kó sì gba ẹ̀dà àṣẹ lábẹ́ òfin láti ṣiṣẹ́. Ẹnití ń buwọ́lù gbọ́dọ̀ fi déètì ìbuwọ́lù síi kó sì fí nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ tàbí àlàyé ìkànsí kan síi.